**ỌJATITUN**
Iwe Isẹgun Ajẹ 4/6d
Iwe Ala nla 7/6d
Işẹdale Yoruba 4/6d
Turari isẹgun Ajẹ 10/6d
Iwe Afọṣẹ 4/6d
Kọ iwe si
Manager,
SHOYINKA,
6,Ojo Road,
Odu-Abọrẹ, Mushin.

# ÌROHIN ÌMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**FUN TITA**
Iwe Itan Igbeyawo Osupa ati Ifẹdiẹ ati Iji Osupa ṣe ntan imọlẹ re sori aiye Oyinmọmọ ni 5/- fun ẹyọkan ati Iwe Adura Akanse ati Apẹrẹ ile Aiye 2/6d. Kọwe si:-
*Lawrence Bamgboye*
28, Upper Offin Lane,
Lagos.

VOL. VI No. 354 MONDAY OCTOBER 29 — NOVEMBER 4 1962 KỌBỌ MEJI (2d)

# Ọkunrin kan ta ẹniti o npari ija fun on ati Iyawo rẹ nibọn

ENUGU:- Ọrọ di pẹẹ n t u k a nigbati Ọkunrin agbẹ kan yinbọn lu Ọkunrin kan ti o npari i j a fun on ati Iyawo rẹ lojiji.

Ni ọjọ A i k u ti iṣe ọjọ kọkanlelogun o ṣ u yi ni Ọgbẹni Okereke Njoku ẹni ọdun marundinlogoji gbọ wipe aladugbo on kan ati Iyawo rẹ nja o si lọ sibẹ lati lọ pari ija na fun wọn. Ọkọ ro'jọ Iyawo ro'jọ bi o si ti bẹrẹsi da ẹjọ na ti ko ti pari rẹ, lojiji ni ọkọ Iyawo sare wọle ti o si gbe ibọn rẹ, ki Ọkunrin na o to sare dide o ti yinbọn si i.

Ọkunrin na wolulẹ o si nyi ninu agbara ẹjẹ. Ariwo ta ge e, awọn enia si sare lọ sọ fun a w ọ n Ọlọpa. Nwọn ti gbe Ọkunrin na lọ si ile iwosan. Awọn Ọlọpa si ti mu Ọdaran na.

nwọn yọ ọta ibọn ni aiya ati ikun rẹ sugbọn k i pẹ lẹhinna ti o fi ku.

Awọn Ọlọpa ti mu Ọdẹ kan fun iwadi.

## Baba kan ni, nigbati ọja ko ta, ni on ba nta "Ọti-Ogogoro"

Arintakiti ni g b o g b o enia nrẹrin nigbati awọn Ọlọpa mu Ọkunrin k a n, Looke Onaibe ti o ngbe ọna Ile-Ifẹ si Ibadan wa siwaju Adajọ Agba kotu kekere Ibadan ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi fun ẹsun pe o nta 'Ọti Ogogoro."

Ọdaran na ṣe alaye niwaju Adajọ pe, nigbati on ti ta oniruru nkan, ti on ko rieyi ti o mu ere wọle ninu rẹ, ni on ba nta "Ọti Ogogoro" nitoripe on ko le jale, ki on si fi agbalagba ara wẹwọn.

Siwaju eyi ni awọn Ọlọpa ti ṣe alaye niwaju Adajọ pe, awọn ri garawa Ọti-Ogogoro m ẹ r i n ninu ile Ọdaran na ninu oṣu ti o kọja yi.

Ọdaran na tun ṣe alaye fun Adajọ pe, ọmọ meje ni on ni, ni Adajọ ba ṣe idajọ pe ki o lọ fi pọnun mẹwa (£10) tanran si kotu tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu mẹta lafarabara.

*CALL AT*
**The Classical Saloon**
365, Herbert Macaulay St., Yaba, (Near St. Agnes Bus Stop.
*For all your hairdressing & Styling, Artificial hair (New and Renewal) Sewing and Machine Knitting.*
Every satisfaction and speed guaranteed
**Mrs. C. A. Kupoluyi**
*(The London trained expert)*

## Ọdẹ ta Ọdẹ nibọn

Idaamu nla ba gbogbo enia nigbati Ọdẹ kan, ṣeesi ta ekeji rẹ ti nwọn jọ lọ si oko ọdẹ ni ibọn.

Ọkunrin na, sọ w i p e ẹranko ni on pe ekeji on, Osuji Enihaone, ẹni ogoji ọdun, nigbati on ri ninu igbo ki on to yinbọn si i.

Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ti gbe Ọkunrin na lọ si ile iwosan

## DICK TIGER BORI !

SAN FRANSICO:- Ọgbẹni Dick Tiger, ọmọ ile Naijiria abẹṣẹku-bi-ojo, ti gba oye Olori gbogbo awọn akanṣẹ, lẹhin ti o ti na Ọgbẹni Gene Fullmer ti o ti fi igba kan gba oyẹ na.



*DICK TIGER*

Ninu ija na, Dick Tiger na Gene Fullmer ni anadojubolẹ ni igba mẹdogun ti nwọn fi ja ija na. Nigbati ẹniti o nfi ọna han, (Refere) ri i wipe oju Fullmer ti bẹjẹ ti ẹjẹ na si koro ni kekere, ti o si tun nṣubu lulẹ bi ẹṣẹ Tiger ti mba a ni gbogbo enia ba gba wipe agbara rẹ ko to ti Dick Tiger, nwọn si pari ija na nigbakẹẹdogun.

IRONUN DI MEJI FUN FULLMER

Bi ija yi ti pari, ti gbogbo enia si bẹrẹsi ki Dick Tiger, ti gbogbo enia ngba a lọwọ, ti nwọn si nki ku orire, ni Gene Fullmer, nlọ tanu-tanu, ni Baba iyawo rẹ, Ọgbẹni Leroy Holt ẹni ọdun mọkandinlọgọta ṣubu lulẹ lojiji, bi nwọn si ti gbe de ile-iwosan lo ba ku. "Ọdun kan ni nkan bani, iya Ọkẹ ku, nwọn tun gba iyawo Ọkẹ,, ironu wa di meji f u n Fullmer ati iyawo rẹ.

DICK TIGER YIO TUN JA

Lẹsẹkẹsẹ ti irohin ti kan an ti gbogbo aiye si nyọ ayọ wipe Dick Tiger di olori gbogbo akanṣẹ f u n gbogbo aiye, ni Ọkunrin Akanṣẹ k a n, Terry Downes, ti on na iṣe o l o r i A k a n ṣ ẹ fun ile Ọba, ti pe, Ọgbẹni Dick Tiger ni ija ni ọjọ kọkandinlogun oṣu kini ọdun ti mbọ yi.

Ọgbẹni Dick T i g e r ti na Ọkunrin na ri ninu ija ẹmẹfa kan ti nwọn ja ninu ọdun 1957.

## ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Ipade g b o g b o ọmọ Ẹgbẹ I m ọ l ẹ Aiye yio wa ni Ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹta oṣu ti mbọ yi 3/11/62, ni agogo mẹta ọsan(3 p.m.)

A fẹ ki gbogbo ọmọ Ẹgbẹ pesẹ fun eto pataki ti a fẹ ṣe fun ipari ọdun ati f u n ọdun titun ti mbọ ni nọmba 16, Bamgbose Street, Eko.

*LATIFU BABALỌLA*
*Akọwe gbogbogbo-a*

AWỌN IWE KOṢEMANI
Iwe Psalmu ati işẹgun ajẹ 2/6 Ẹyọkan, 24/- Dọsini kan. Iwe Acura lati bori gbogbo isoro 2/-6d Ẹyọkan, 24/ Dọsini kan. Iwe Itumọ Ala - 2/6 Ẹyọkan, 24/- Dọsini kan.
Kọ iwe bere awọn iwe miran ti o nfẹ. Fi owo ranṣẹ si:-
OLOTU,
P. O. BOX 236,
EBUTE METTA, NIGERIA

BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TONIKI TITUN TI OSESE DE TI NWON NPE NI:-

"DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJEBIDAN FUN EGBOGI AGBALAGBA OKUNRIN ATI OBINRIN GBOGBO




Dynamiren je Ojulowo Egbogi Ajidewe hounhaun ti awon Jamani nse wa fun tita ki ogun (War) ti awon Geesi pelu won to sele, Lehin igbana a ko ri irufe egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti ise re si daju be yen mo ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa tanse si awon Ogbologbo Dokita wa nilu Jamani pe ki nwon se iwadi awon elegbogi "Dynamiren" bi nwon ba si mbe laiye, nwon si da esi pada wipe nwon nbe ati pe egbogi na ti a nfe lodo won wa pelu' Eyi mu inu wa dun pupo julo nitoripe awon Onibara wa mo daju wipe kosi nganu ninu gbogbo egbog wa rara. Egbagbeje irufe re wa kakiri sugbon bi ti eleyi ko. Bi are ara ba mu o, nigbakugba fun wahala tabi ise se ti o ko ba jeun daradara, tabi ki o ma le sun de bi kan losan tabi loru tabi awon isan ara re gbogbo" ko ba sise daradara are E-emi (breath) inu ko ba gunle daradara to nitoripe ise tabi wahala sise ko "NJE" fun won n, ailera gbogbo wonyi ti ojo ori re (age) ba ti koja O'gbon ocun lo si dede adorin tabi jube lo mo daju pe 'DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfe lati so ara re di Otun patapata, oju re a si jolo, eran ara re ti o ti hunjo yio bere si dan pada. Ara re yio ma gbe kankan nigba kugba "Are" nigbakugba yio salo patapata pelu.

Igbadun ati Alafia yio de si o.

Bere egbogi na ni Sobu awon:-

NIGERIAN MEDICINE STORES:
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE 20278.

**Waterloo Medicine Stores,**
**8, Palmchurch Street, Lagos.**
**Phone: 22878 Nigerian, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS,
48, WAKEMAN STREETPHONE 22878 YABA.

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO




## YE IRAWO RE WO

Eyi ni awon nkan ti yio sele si o larin ose yi.

AQUARIUS (JAN 20 – FEB 18) Mase reti iranlowo lati odo enikan larin ose yi. Torina rauti ara re.

PICES (Feb - Mar 20) Aeiri re ko ni tu rara lose yi, mase jiyan tabi jampata, iwo yio gburo ise kan ninu ose yi.

ARIES (Mar 21 - Apl 19) Ose yi yio le fun o, bi iwo ko ba fi wara wara jaiye. Iwo yio bori gbogbo isoro re oro re. yio dara lowo obinrin ti o mba soro.

TAURUS (Apl 20 - May 20) Sora re larin ose yi nitoripe erokero yio maa so si o lokan Orisirisi ajeji ati abami enia ni iwo yio ma a ri, mase jafara pelu won, ma si se gba won laye. Sise re bi o ti to.

GEMINI (May 21 - July 20) Ipo ti asiki re wa lose yi dara jojo awon enia yio maa se alatilehin fun o ninu gbogbo nkan.

CANCER (Jun. 21 - July 20) Mura lati lowo si oro ipade kan ti nwon o pe o si, ipade na yio si je nipa aworan tabi nipa ijo.

LEO (July 21 - Aug 22) Mase j e k i ayo pa o lori ninu ose yi, ki o si yara tete ma a se nkan, nisise bayi gbogbo nkan re ni yio je daradara.

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Isora di owo re, ki alejo mase ba alamori re je, iwo yio jere ninu ise re ati larin egbe

LIBRA (Sept 23 - Oct 22) Gbogbo alamori re yio dara l o s e yi, ati alamori ara re paapaa. Ose yi dara fun o, sugbon ki o sora lodo awon ti o mba sise

SCORPIO (Oct 23 - Nov 21) Fi ara bale die ninu ise re ki o si simi, ki o si rin mo awon gbajumo enia, obinrin ti o mba s o r o yio gba ife fun o

SAGITTARIUS (Nov 22 - Dec 21) Bi o ba le ni aforiti gbogbo ohun ti o ngbero ni yio se. Iwo yio ri obinrin ateta fe.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 19) Sora re, nitoripe, ore re kan yio da o, nitori ija kan ti yio sele larin nyin, ki o si maa se inure si awon enia re, ki o si ma a fun won ni owo pelu oro re yio si dara pelu

## ITUMO ALA

Lati owo- Baba-Alala, Eko

1. Ti o ba la ala wipe imu re ge, ti o ba wa ninu aisan. iku ni aisan na yio yori si.
2. Ti o ba la ala wipe imu re di meji, o bi ibeji omo ninu odun na.
3. Ti aboyun ba la ala wipe egbo mu on ninu imu, ki o sora ki o ma ba ku pelu o m o inu re.
4. Ti o ba la ala wipe eti kan ni o ni, se opolopo sara, nitori iku ojiji.
5. Ti o ba la ala wipe o nje e-eri eti re, iwo yio bi omokunrin ninu odun na.
6. Ti o ba la ala wipe eje nda sile ninu imu re, mura daada iwo yio je haramu owo kan ni asiko na.
7. Ti o ba la ala wipe o nje omo ika sora ti o ba wa ninu aisan, ti o ko ba mura iwo yio ku.
8. Eniti o ba la ala wipe on siwaju isin fun awon enia' iwo yio gba oye ninu esin lodo Olorun.
9. Ti obinrin ba la ala wipe on je asiwaju, ninu esin, ti ko ba sora gidigidi yio ku ninu odun na.
10. Ti enia ba la ala wipe on ri baba on loju oorun, yio mo asiko na si daradara.

KERE O

Kurani L'ede Yor
TI DE

A nta Kurani ogbon ti a se ni Larubawa ati mo re l'ede Yoruba, O fun enikeni.

25/- Postage 1

Iwe Egbogi iwosan At baiye, o kun fun Awure, ri itumo ala ati ohun ti rumiloju ninu Odu merin logun ninu iwe kanga.

**10/6d Postage**

*TETE FI OWO TIRE SE SI:—*

ESAN KOGBOGU
SERVICE.

*8, Idumagbo Avenue, L*
*Nigeria.*

**IBI IJOI**
**AUSTIN**
**TO FI N**
**DINKU**
**MOTO-V**

Moto A
moto la
ki ise r
un o.M
siko; jig
daj ojuf
dere pe

E O!
de Yoruba
DE
ni ọgbọn-Fun
ubawa ati itu-
ruba, O wulo

age 1/6d

Postage 9d

GBOGUN
ICE.


## Akiyesi Pataki

### Sengovan Tablets! Sengovan Tablets!!




SENGOVAN TABLET.- Jẹ ajidewe egb gi fun awọn agbalagba ati ilera ati gẹgẹbi Ọmọkunrin

SENGOVAN:- Jẹ ọkan pataki ti a ṣe iwadi ni ilu Okere ni ilẹ Jamani lọwọ ọkan ninu awọn Ọjọgbọn Oniṣegun Arẹmọ ti ilu Western Jamani fun arẹ ara eyiti ọjọ ori re to Ogoji si Ọgọrin ọdun (40-80 years).

SENGOVAN:- Jẹ egbogi ti o ti wa lojo pipẹ fun anfani awọn agbalagba ilu Jamani ki a to ṣeamuwa rẹ si ilu Naijiria Ajẹbidan ni ogun yi.

### Irohin ko to Afojuba

Bere:- A o ri lọwọ awọn Oniṣegun Adugbo rẹ

Asoju:- Hassan Commercial Medicine Stores
26, Bishop Street Lagos.
Phone: 23745 Lagos.



## Akiyesi Pataki

Lẹhin nkan bi ọdun mẹfa sẹhin ti nwọn ko ṣe wa mọ rara, egbogi oju na tun wọ ilẹyi. Bere:—

### "COLLYRIO PAGLIANO"

Bi amodi tabi aisan "OJU DIDUN" ba nyọ ọ lẹnu nibakugba tabi fun ọjọ to ti pẹ jọjọ, yẹ ẸJẸ ARA RẸ WO nipa lilo egbogi atata ti o daju fun ẹjẹ ara RICHALET lẹhin na ẹwẹ, ki o si ra egbogi ti awọn ara ilu Tatambulu (Italy) ṣe lati ma a kan si oju na pẹlu, ti a npe ni "COLLYRIO PAGLIANO" fun oju didun, Meji rẹ ko si ni igboro ilu Naijiria.

Ṣe iranti wipe oju ni baba ara o, ijafara si lewu pẹlu Bere ni Ṣọbu awọn Olori egbogi Jamani igboro Eko ti nwọn npe ni:—

**Waterloo Medicine Stores**
**Continental Medicine Specialist**
8, Palm church Street, Lagos P. O. Box 333,
Phone : 22878, Lagos Nigeria. (Oja ita Faji)



# JOKO AWAMỌTO INU IN S 200 DARA TOBẸ NMU ARẸ AWAMỌTO U PUPỌPUPỌ O NMU O-WIWA RỌRUN PẸLU AISI EWU!



to Austin to lagbara yi tunbọ nṣe alekun wiwato laisi ewu nitoripe a ti ṣee dara tobẹ, eyiti yio jẹṣe rẹ jafafa siwaju si i, ki ere si ma wọle pupọ ọ. Mọto S ati T 200 ni inu fifẹ to si balẹ fun ẹru; jigi iwaju rẹ lagbara, o si ngẹki enia riran daojuferese rẹ nịẹki mọto ṣe wo fẹhinrin laisi ewu pẹ ki awa a wo ki o ri i.

**AUSTIN S 200**

Nigeria Head Office: 237 — 241 Igbosere Road, Private Mail Bag 2083, Lagos. Garages at Abe, Apapa, Benin, Enugu, Ibadan, Jos, Kano, Lagos, Onitsha and Port Harcourt.

**SCOA Motors**



## KEREO! AKIYESI PATAKI!!

Awa na le jẹri wipe Ojulowo haunhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana) pẹlu, meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi kakiri Ilu Naijiria




### Irohin kkiri Igboro Ilu Eko

Bẹ na ni ẹwẹ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia t'ọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn si fi ṣe ọrọ ati orin kiri a a wọp jẹ nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS.

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to, ti o jẹ Ojulowo gidi ati iamat ṣe fun iwosan "JẸDIJẸDI" bi o ti wu ki ọjọ re pẹ to bẹ ni ti awọn le tun fi owo sọ tabi ṣe ileri fun gbogbo awọn ti amodi b Iju, Igbẹ sise, tabi aiko ni igbonsẹ deede, Inu rirun, nigbakugba ara wiwo, Ẹsanti, Ẹhin didun, Oju sisan, tabi aiko miran kekere bo bu ruku lara, Oṣi inu Origbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu "Wipe" nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn ba nlo Egbogi LEOPILLS nitoripe a si tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa siso di ọtun patapata.

ṢE IRANTI PE ALAFIA L'OGUN ỌRỌ, IJAFARA SI LEWU PẸLU (POSTAGE 1/9d)

**IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:- Igo nla ṣile mẹfa abọ.** (6/6d) pere ni, Igo kekere ṣile mẹta abọ (3/6d) pere ni

Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi Amodi ti o ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

**Waterloo Medicine Stores**
8. Palm Church Street, P. O. Box 333. Lagos Nigeria Phone 22878, ati pẹlu ni Ṣọbu awọn arabinrin Mrs. C. O Babajide near Health office Ibadan ati ni Abimbọla Medicine Store B29 Okesha Street Ilesha. Bisale Medicine Stores, British & Foreign Medicine (Dealer) S. W. 6/458 AGBOKOJO STREET, IBADAN N. o

AKIYESI:- Ri daju gbangba wipe Ṣọbu ti nwọn nta la gbe ranṣẹ lọ ra, bi bẹ ko awọn ẹlomiran yio fi ERU lọ ta Adamọdi tabi orisi omiran fun ọ o, maṣe gba rara o.

# IDIJE ! IDIJE !!

A fi eyi kede fun gbogbo awọn Onkawe IROHIN IMỌLẸ ati awọn Ọmọ karọ-o-jire pe

a nfẹ **ITAN LEDE YORUBA**

Eyiti ẹnikẹni ko ti tẹ jade ninu iwe ri tabi ti nwọn ko ti sọ lori ẹrọ Redio ri; ẹnikẹni ti o ba si bori yio gba:—

PỌNUN KAN ṢILE KAN **(£1 : 1/-)**

*AKIYESI-* Kọ itan rẹ ki o han rekete, ti ẹniti ko ba han ao fa a ya ni, ki o si mọ dajudaju pe ko ni ipin ninu Idije na ITAN ẹniti o ba si dara ju ni ao tẹ jade ninu IWE IROHIN IMỌLẸ yi, ao si fi Pọnun kan Ṣile kan (£1 : 1/-) (Postal Order) ranṣẹ si i. A ko kọ ọnọọde tabi agbalagba.

Fi Stamp Tọrọ **(3D)** ranṣẹ fun gbigbe Pọnun kan Ṣile kan £1 : 1/-) ti o ba jẹ pada si ọ, ki o ge ilati Idije yi wa, ki o si fi ranṣẹ pẹlu Stamp Tọrọ rẹ si wa. Ẹnikẹni ti ko ba ge Idije tirẹ ranṣẹ si wa, ti o ba jẹ owo na a ko ni fi ranṣẹ si i, a ko si ni fun un ni Stamp Tọrọ rẹ

Idije yi yio pari ni ọjọ kini oṣu kejila ọdun yi. Ao tẹ itan ẹniti o ba dara jade ni ọjọ kẹta oṣu kejila ọdun yi (3/12/62).

*ORUKỌ*______________________________

*IBUGBE*______________________________

______________________________

Fi itan rẹ ranṣẹ si:-

OLOTU IROHIN IMOLE
16, Bamgbose Street, Lagos.



BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI A NPE NI:-

## "UROXAL"



Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney-Blader fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ o lẹnu Ehin didun eri ile itọ tabi itọ-jijo enia, itọ riru ruku-ruku pipọn tabi rirun, lakuregbe Ibaradi wiwo, orunku, ọwọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju aiko le gbe ara kankan tabi kiakia didaji loru nigbakugba, ati oriṣiriṣi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ ko si ni ilu Naijiria nitorina ṣora ki awọn oleru tabi awọn oni rọbirọbi ma ta oriṣi omiran ti ko ni lari fun ọ ma ṣe gba a rara o! Owo rẹ jẹ ṣile mẹjọ abọ (8/6d) owo ọkọ ṣile mej abọ (2/6d) bere egbogi yi ni ṣọbu awọn Saro ti nwọn npe ni:

NIGERIAN MEDICINE STORES:
4, TINUBU STREET, LAGOS, PHONE 20278.

**Waterloo Medicine Stores,**
**8, Palmchurch Street, Lagos,**
**Phone: 22878 Nigerian, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS,
48, WAKEMAN STREETPHONE 22878 YABA.

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA


# Bawo ni o ti dara to, lati jumọ gbe ni irẹpọ ?

Olotu,

Gbami laye lati kan sara si gbogbo Ọmọ-Yoruba ilu Eko ati agbegbe rẹ, ti nwọn rori wo, ti nwọn parapọ dibo fun ẹgbẹ Afẹnifẹre, ti a mọ ni ẹgbẹ Ọmọ Yoruba nilẹ Naijiria, awọn ti nwọn gbe ẹgbẹ Afẹnifẹre de ori akete akoso Ijọba ibilẹ ilu Eko lati Ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdogun Oṣu yi. Oluwa ko ni jẹki o re nyin Aṣẹ.

### ADIẸ TO KU, O TUN LE JẸ AGBADO

Iṣẹgun ti ẹgbẹ Afẹnifẹre ni lori ibo ti nwọn di kọja nilu Eko, ki iṣe mimọṣe wọn, bikoṣe wipe o wu Ọlọrun Olodumare, lati fi han ẹda wipe, on ni Ọba to nṣọ Oku di alaye lori ero ọkan ẹda



*ỌMỌ ỌBA "ẸRUKOBODO" Eko*

to ti han si agbaiye wipe, ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ku. Ọlọrun fi ibo na ṣe apẹrẹ wipe ẹgbẹ Afẹnifẹre ko ku, o ṣẹṣẹ fi ẹsẹ rinlẹ ni ati pe, bi o ti fi ẹsẹ rinlẹ ninu ilu Eko yi, bẹ ẹ na ni ẹsẹ rẹ yio rinlẹ kari ilẹ ka a to ẹo jire, nitoripe, Ẹyin iwaju ni tẹhin nwo sare.

### IRẸPỌ LODUN

Itumọ gbolohun Owe yi ni ngo tun fi siwaju ẹnyin Ọmọ Yoruba, eyiti mo ri pe, yio tun mu irẹpọ wa dagba s'oke si gẹgẹbi ipinnu wa.

Ni aiye ijọun, Ọkunrin kan mbẹ, o ni Obinrin kan, ko si ẹniti Ọkunrin yi nba damọran to ju iyawo rẹ yi lọ, o ba iyawo rẹ yi damọran,, o ti bẹ di olowo, nigbati ọkan Ọkunrin yi balẹ tan, o lọ fẹ iyawo miran, lati ọjọ ti iyawo to tun fẹ yi ti dele, ni ko ti ba iyale rẹ damọran mọ, iyawo tuntun lo ku to tun nba damọran.

Nigbati iyale ri i wipe, ọkọ on ko tun ba on damọran, mọ, iyawo lo ṣẹṣẹ fẹ lo tun nba damọran, inu bi iyale, depo ti o fi lọ fi ọrọ na han awọn agbalagba, awọn agbalagba si sọ fun un wipe, ki ohun ti o nfẹ binu si yi, ko to ohun ti o le binu si, ohun to lọ to'le ṣe ni wipe, ki o lọ ra Aja kan ,ki o sọ orukọ Aja na ni "Aramikogbayi" Bi o ba ṣe bẹ, ki o foju silẹ wo ibiti ọrọ na yio yọri si.

Kini iyale gbọ bẹ si, lẹsẹkẹsẹ, o lọ ra Aja kekere kan, o mu wale, o sọ ni "Aramikogbayi"

Nigbati o ri wipe, ọkọ pẹlu Iyawo rẹ lọ joko, ti nwọn ndamọrau, Iyale bẹrẹsi pe Aja rẹ:- "Aramikogbayi" "Aramikogbayi"

Nigbati iyawo gbọ orukọ ti Iyale fi npe Aja rẹ, inu bi i pupọ depo ti on na dide lọ fi ọrọ na han awọn agbalagba, ohun ti nwọn ni ki on na ṣe ni pe ki on na o lọ ra Aja tirẹ, ki o sọ orukọ Aja na ni, "Iwọ na a lọ ni" lojukanna, iyawo lọ ra Aja tirẹ, o mu wale.

Nigbati ọkọ pe e, ti nwọn bẹrẹsi damọran gẹgẹbi nwọn ti nṣe lati ẹhin wa, iyale bẹrẹsi pe orukọ Aja tirẹ "Aramikogbayi" iyawo na npe aja tirẹ "Iwọ a lọ ni" Nigbati ọkọ wọn ri i pe, awọn iyawo on nfẹ da bilisi silẹ, nipa orukọ aja wọn yi, ọkọ wọn na dide on na lọ fi ọrọ na han awọn agbalagba ohun ti nwọn sọ fun ọkọ wọn nipe nigbati ọrọ ri gẹgẹbi o ti ri yẹn, kosi ohun to le ṣe to le fi tu awọn iyawo rẹ ninu, bikoṣe wipe, ki on na lọ ra Aja tirẹ, ki o sọ orukọ rẹ ni, "Irẹpọ lo dun"

Nigbati ọkọ ra Aja tirẹ to sọ lorukọ tan, o tun pe Iyawo lọ si ibiti nwọn ti ndamọran, bi iyale ti ri wipe, ọkọ pẹlu iyawo ti lọ joko sibi ti nwọn ti ndamọran, o bẹrẹ si pe Aja rẹ "Aramikogbayi" Aramikogbayi" Iyawo na npe Aja tirẹ "Iwọ, a lọ ni" Iwọ, a lọ ni" Ọkọ wọn paapa npe Aja tirẹ, "Irẹpọ lo dun" "Irẹpọ lo dun" Nigbati Iyale ri i wipe, gbogbo bi on ti nṣe to, eyi ti o le mu ọkọ awọn ko binu, ko fi bẹ binu, bi o kanran ko binu a fi orukọ Aja rẹ tu awọn mejeji ninu ka ni, lojukan na ni iyale ti pe iyawo, o sọ fun un wipe, orukọ Aja

(Wo oju ewe keje)

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

*Lati Ọwọ EJON'GBORO*

**ETI RẸ MELO ?**

*A nta awọn Ọja wọnyi nihin:-*

Iwe Adura Tetedamilohun 5/-
Iwe Ifa Agbọnmilegun ati Yantin tite £1 : 5/-
Aajo Ilu China fun Itaja £2 : 10/-
Iwe Egbogi Ajẹbidan £1 : 10/-
Iwe Itumọ Ala pelu Iwadi nkan 15/-
Aajo Isọye fun Iwe-Mimọ £1
Abẹla Aragoni 15/-

MANAGER,
14, Alhaji Alayaki Street,
Mushin Lagos.

## ILESHA

Jinnijinni dabo gbogbo enia nigbati ọkunrin kan, Thomson Ọlalẹye, ti o ngbe ọdọfin, kọlu mọto akẹru kan lori kẹkẹ ologere, o si ku loju kanna.

## KADUNA

Ọlọla Kashim Ibrahim, Gomina Ipinlẹ Ariwa, fun awọn Obirin marun ni pọnun mẹta mẹta (£3 each) nitoripe ẹnikọọkan wọn bi ọmọ mẹta mẹta larin ọsẹ ti o kọja yi.

## EKO

Awọn Ọlọpa ti bẹrẹsi wa obi ọmọ ile-iwe kan ti mọto (L.D 1906) pa nigbati o nbọ lati ile-iwe ni opopo Marina. Nwọn ko ti ri obi tabi ẹniti o mọ ọmọ na nisisiyi.

## HANNOVER

Ọgbẹni L. L. Barhu ti iṣe akowe awọn ẹgbẹ osiṣẹ ati ọgbẹni E. O. Ọdẹyẹmi ti ba ọkọ ofurufu gunlẹ silẹ yi, fun ipade kan ti nwọn lẹ ẹe n ilẹyi.

## OWERRI

Ọjẹ buruku ẹni gb'omi wẹ, Ode kan ṣeẹṣi yinbọ si ekeji rẹ, Osuji Emerole ẹni ọdun marundinlọgọta. O si ku bi nwọn ti ngbee lọ si ile-iwosan.

## LONDỌNU

Adajọ ṣe idajọ pe ki ọdaran kan, Janathan Olubamigboye, ẹni ọdun marundilọgoji lọ si ẹwọn osu mẹfa nitoripe awọn ọlọpa ba ewe taba IGBO lọwọ rẹ.

## ENUGU

Ọgbẹni Francis Okonkwo ti o nṣiṣẹ ni ilẹ-ifiweranṣẹ Enugu ni awọn Ọlọṣa lu ni aludamoku, o si wa ni ile-iwosan Enugu nisisiyi.

## PORT HARCOURT

Idaamu nla ba gbogbo awọn olugbe Akasa leti Port Harcourt nigbati iyawo-ile kan, Beniana Okocha, lọ wẹ ni kutukutu Owurọ ti o si ṣubu si baluwẹ. Lesẹkese ni nwọn gbe lọ si ile-iwosan nibi ti o ku si

## KẸNYA

Ijọba ti pa a laṣẹ pe ile-iwe awọn alawọfunfun mẹdogun yio ma a gba gbogbo awọn Ọmọ.

Ki iṣe Ọmọ alawọfunfun nikan ti awọn obi wọn ba ti le san'wo.

# EYI NI ỌJỌ ỌJA ILẸ YORUBA

### ỌJỌ AJE OCTOBER 29 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Mushin |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowo, Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun - Ọwa, Erunwọn, Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

### ỌJỌ IṢẸGUN OCTOBER 30 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Ikẹja, Agege, Ebute-Ero, Ọjọ Ajido |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla, Ajegunle, Idọgọ |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ, Owode, Igbo-ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹsha-Ijẹbu, Isara, Imodi |
| IJẸSHA | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Ijebu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiemi |
| EKITI | Okemesi, Ifaki |

### ỌJỌ'RU OCTOBER 31 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Oyingbo, Ejinrin |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN | Akeroro, Idofin, Lagun, Ṣagbe, Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode - Rẹmọ |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi - Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilarọ, Oja - Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

### ỌJỌ ỌJỌBỌ NOVEMBER 1 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Ikosi, Ẹpẹ |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdegbo Oyedeji, Ogburo, Egbẹda, Babalokuta |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe, Ishan, Isara, Imodi |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọ Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo - Aiyedun |

### ỌJỌ ẸTI NOVEMBER 2 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Mushin, Badagry |
| ABẸOKUTA | Otta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowọ, Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa, Erunwọn Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| EGBADO | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

### ỌJỌ ABAMẸTA N VEMBER 3 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Lgege, Ikẹja |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla, Ajegunle, Idọgọ |
| IBADAN | Aalupọn, Ajegunle, Owode, Igbo-ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imuṣhin, Agọ-Iwoye, Ijẹsha, Ijebu, Isara Imodi |
| IJẸSHA | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Ijẹbu,-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemsi,e Ifaki, |

### ỌJỌ AIKU NOVEMBER 4 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ILU |
|---|---|
| EKỌ ATI AGBEGBE RẸ . | Oyingbo |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Iberẹkodo, Asu, Wasimi, |
| IBADAN | Akeroro, Idofin, Lagun, Ṣagbẹ Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaosu, Ogere, Irọlu, Itele, Ode - Rẹmọ |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi - Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilarọ, Oja—Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

### ỌJỌ AJE NOVEMBER 5 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ . | Ọbun - Eko, Ojuwoye |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabẹ, Ọdeda, Ibara |
| IBADAN | Fedẹgbo, Oyedeji, Ẹgbẹda, Babalokuta |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope Iṣara, Imodi, Ishan |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọ Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo—Aiyedun |

## Bawo ni o ti dara to, lati jumo gbe ni irepo ?

*Lati Oju-ewe Kefa*

mi ti o gba si ibinu yi, ki şe iwọ ni mo fi nba wi, ọkọ wa to fi mi silẹ ti ko ba mi damọran mọ ni mo nfi orukọ Aja na pa owe mi mọ, mo si pa owe na mọọ bi o kan'ran ki o binu o tun fi orukọ Aja rẹ tu awa mejeji ninu ni, nitorina emi pẹlu rẹ kişe onija, ọrẹ ni ki a jọ ma a şe.

Lati ọjọ na ni iyalẹ ati iyawo ti mba ara wọn lopọ gẹgẹbi ọmọ iya. Nitori kini? Nitoripe ọkọ wọn fi ọpọlọpọ suru da ifẹ wọn pọ.

OMO-YORUBA

Ọrọ ti o delọ si awa ojulowo ọmọ Yoruba yi, ki'şe ohun ti a le fi şe ibinu tabi ohun ti a le fi ma a ba ara wa ja ija ainidi, ti ko ni fun wa ni aye lati ni irẹpọ laarin ara wa. Emi ti ri i daju pe, ti a ba le şe ara wa ni Oşuşu-ọwọ, gẹgẹbi a w ọ n Ọmọ-Yoruba Ilu-Eko ati agbegbe rẹ ti şe koja ninu ibo ti nwọn di koja laipẹ yi bi o ti wu kori, ni alaiko şe iyemeji, bi Oluwa ba fẹ; Tọnakọna ni ao ma a ri Oşuşu-ọwọ na fi gba ọpọtọ iya ati iwọsi kuro lọna fun awọn arọmọdọmọ wa to tun mbọ lẹhin ọla.

## IKU 'MU ENIRE LỌ !

ABẸOKUTA:- Laipẹ yi ni Ọgbẹni Daniel Ayọọla Adekunle Akinşọla fi ilẹ-şe-aşọbora, gbogbo ilu ni o ndamu nigbati nwọn gbọ iku baba oninure na. Awọn Ijọ "St. Judes Anglican" Ikija Ibẹrẹkodo, Abẹokuta ni nwọn gbe Oku baba oninure na lọ sin, Ogunlọgọ enia si pẹlu wọn de ibusun igbehin rẹ.

Oku na jẹ eni Ọdun mọkandinladọta (49 years), o si fi awọn Ọmọ marun silẹ l'ọkunrin ati l'obinrin s'aiye lọ. O jẹ oninu rere, o ni Ọyaya, o lawọ, o si fẹran ẹsin pupọ nigba aiye rẹ.

Alufa EniỌwọ, Olu Abiọdun lo şe isin isinku na, o si sọ ọpọlọpọ işẹ iwuri ti Ologbe na şe ni Abẹokuta ati ni Eko nigba aiye rẹ.

A ki iyawo Ologbe na, Iyaafin Mopelọla A l a k ẹ Ọmọ ati awọn ọbi ti o fi silẹ. Oluwa yio tu nyin ninu o, yio si da awọn Ọmọ rẹ si Amin o.

## Aboyun kan wẹwọn oşu mejila

ADO-EKITI:- Laipẹ yi ni Adajọ kekere ilu Ado-Ekiti şe idajọ ẹwọn o ş u mejila fun A b o y u n kan, Florence Faderera, nitori ẹsun ole jija.

Ẹsun ti awọn Ọlọpa mu ọdaran na fun ni wipe, o fọ Şọọşi "St. Stephen Anglican Church" Ado-Ekiti, lẹhin isin owurọ ọjọ Aiku kan ni arin oşu ti o kọja yi, o si ko owo ti apapọ isiro rẹ jẹ pọnun mẹrinlelọgbọn şile mẹrinla ati kọbọ mẹrin (£34:14s:4d) eyi ti işe owo-igba ti awọn I j ọ Şọọşi na da pẹlu apo ọgẹdẹ kan ti işe ti ọkan ninu awọn agba Ijọ na.

Adajọ na si tun şe idajọ pe ki awọn obinrin meji kan, Ẹbun Fọlọrunshọ ati Esther Fọlakẹ, ti nwọn mu pẹlu Ọdaran na ma a lọ ni alafia nitoripe kosi ẹri pataki pe nwọn ni ọwọ ninu ẹjọ na.

## Kini U. A. C. fi han wa ?



OGBENI ADEKUNLE OJỌRA
*Ọga-Agba Ile-işẹ U. A. C.*

EKO:- O h u n ti awọn U. A. C. fi han wa li ọjọ na ni, iru işẹ ribiribi ti nwọn ti şe ninu işe ọwọ ati işẹ Akọwe fun idagbasoke ilẹ Naijiria.

Pataki ohun ti nwọn fi han wa ni isọ ti wọn ni, awọn nkan ti oju gbogbo aiye nwo, ilẹ Naijiria ti o şeşẹ dide, ati awọn oja ti o nti ilẹ na jade.

Orişirişi awọn işẹ ọwọ ti awọn Oyinbo U. A. C. na nşe ti o jẹ anfani fun ilẹ Naijiria ni a fi han ninu isọ wọn lọjọ na.

## ỌMỌ TITUN ALEJO AIYE

MUSHIN:- Irohin ko to afojuba ni ti Ikomojade Ọgbẹni J. O. Shoyinka oga oniwe Irohin Y o r u b a. abigẹgẹ kuubi ojo; onilan Ajiran ilu awọn oku, ati Iyawo rẹ Iyaafin Aşakẹ Shoyinka ti gbogbo enia mọ ni "Iya—Bọsẹ" ti Ọlọrun fi ta wọn lọre ni ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ kẹfa oşu yi ni Nọmba 6, Ojo Road, Mushin.

Nigbati o ti ku ọjọ mẹrin ni awọn ero ti bẹrẹ si de lati Ibẹrẹkodo, Idọgọ, Wasimi, Owode, Ọtta, Ifọ, Abẹokuta, ati bẹbẹ lọ. Nigbati ọjọ ọmọ kiko pe, awọn ẹgbẹ Ifẹtayọ ti işe ẹgbẹ baba ọmọ fọmọyọ lọjọ na. Eniọwọ F. A. Abati ti işe A l u f a Ijọ "African Church Mushin" ni o sọ ọmọ na lorukọ, nwọn si sọ ni Iyabọ Titilọla Bọlanle.

Baba ọmọ na Shoyinka ati Aşakẹ iya ọmọ na ati awọn ẹgbẹ Ifẹtayọ pẹlu gbogbo awọn alabaşẹyẹ ọjọ na jumọ njo papọ bi kokoro ni, irohin ko to afojuba ni ẹyẹ ati adun ikomọjade na, orişirişi onjẹ adidun, ọti, obi i, bia, sitaotu, ẹmu, ẹguro, siga ni baba ọmọ na fi tẹ awọn alabaşẹyẹ ọjọ na lọrun.

Nigbati inawo na bẹrẹ nşe ni gbogbo ilu bẹrẹsi rọkẹkẹ fun inawo ọjọ na. Ni deede aago mẹrin irọlẹ ni ẹsẹ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Ifẹtayọ o pe sanmusamu pẹlu onilu wọn.

Awọn ẹgbẹ na wa bẹrẹsi jo yi gbogbo ilu Mushin ka pẹlu aşọ wọn titun ti nwọn şẹşẹ da. Ọgbẹni Laisi Ayinla "Onilufaji" ti işe onilu ẹgbẹ Ifẹtayọ fi kọkọrọ ilu rẹ dara ni ọjọ na, faaji ọjọ na bua - aya ole gongo.

Diẹ ti aye wa fun ninu awọn enia jankanjankan ti o wa nibi isọmọ lorukọ na niwọnyi:-

Oyetunji Adeọşun, Latifu Babalọla, Adekunle Adeniji, Adewale Adewunmi, Ọmọniyi Ọmọlẹyẹ, Comfort Oyeriode, Alakẹ Adelaja, J. O. Williams A. K. Adelẹyẹ, J. B. Ayantunde, M. O. Aderibighe.

Ki Oluwa da ọmọ na si, ki o fi rere kari g b o g b o awọn alabaşẹyẹ na. Amin o.

## ỌPẸ LO NI FẸDIRA !



EKO:- Gbogbo ile ati ode lo kun fun Ogunlọgọ awọn ero, ti nwọn wa wo'ran Ipade kini ti Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko şe lẹhin ti Ẹ g b ẹ Afẹnifere (A. G.) ti ko aye Ijoko mẹtadinlọgbọn, ti Ẹgbẹ Alakukọ (N. C. N. C.) si ko aye medogun yoku.

Ninu ipade na, Ọlọlu Adeniji Adele, ti işe Alakoso Igbimọ Eko, ki gbogbo awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifere ku orire, o si tun ki ẹgbẹ Alakukọ na pẹlu. Ninu ọrọ rẹ, Adeniji Adele şe alaye wipe on ko fara mọ ẹgbẹ Oşelu kankan, nitoripe baba gbogbo wọn ni on. Lẹhin eyi ni gbogbo wọn fi imọ şọkan ti nwọn si yan Alhaji A. F. Masha ni Alaga.

Alhaji Masha lo njuwọ si awọn enia ninu aworan yi.

*Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS*
*16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495, Phone 21985, Lagos*
*Olotu: E. A. Adeniji 24, Oluyide Street, Odu—Abọre Mushin.*